# IDUPẸ ONIGBAGBỌ́

## Orin Dafidi 107:1-43

## ẸKỌ 47 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Enia iba ma yin OLUWA nitori ore rẹ̀" (Orin Dafidi 107:21).**

### Ominira lati Jọsin

Nigba ti awọn Baba wa Arinrin-ajo wa si ilẹ Amẹrika lati ni ibugbe nibẹ fun ara wọn ni ilẹ titun, wọn n wa ibi kan ti wọn o gbe sin Ọlọrun ni ododo ati iwa-mimọ́ tootọ́. Wọn kò bikita pe kò si ilu ti wọn o dé si, tabi ilé-itajà nibi ti wọn o gbe ra awọn nkan ti wọn kò le ṣe alai ni fun anfaani ara wọn. Wọn mura tan lati fara da iṣoro ati iya, ki wọn si fara mọ iba diẹ ti wọn le ṣe fun ara wọn, ki wọn ba le ni ominira fun ẹmi wọn lati le sin Oluwa gẹgẹ bi ọkan wọn ti jẹ wọn lẹri pe o tọ̀na.

O ṣoro fun awa ti a wa ni ilẹ ominira lode oni lati gbagbọ́ pe ki i ṣe olukuluku eniyan ni o ti ni anfaani eyi ti awa ni lati lọ si ile-ẹsin ti a ba fẹ́, nigbakuugba ti o ba wu wa. A o tubọ kun fun ọpẹ si i fun awọn ibukun Ọlọrun bi a ba le duro lati ronu iṣẹ́ ati omije awọn oloot ọ eniyan mimọ́ Ọga-ogo ti wọn mura tan lati kú ju pe ki wọn ju igbagbọ́ wọn ninu Ọlọrun Olodumare silẹ. Itan sọ fun wa pe ẹẹdẹgbẹtala ọkẹ (50,000,000) eniyan ni o kú iku ajẹri-kú nitori wọn mu iduro wọn fun otitọ Ọrọ Ọlọrun. Wọn kú iku ailaaanu ati ikú ikà: a kan wọn mọ agbelebu, a fa wọn ya nigba ti wọn n bá ẹranko jà, a fi iná sun wọ́n, a fa apá tabi ẹsẹ̀ wọn ya kuro lara wọn – **nitori** wọn kọ̀ lati sẹ́ igbagbọ́ wọn ninu Kristi, ireti wọn fun iye ainipẹkun. Wọn rekọja lati lọ wà pẹlu Jesu, wọn si gba ère ologo, nigba ti awọn ti o n fẹ lati pa Ẹsin Igbagbọ́ rẹ́ yoo jiya ninu iṣẹ́ oro titi ayeraye ninu ègbé.

### Igbẹkẹle ninu Ọlọrun

Awọn Arinrin-ajo wọnyii ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun pe yoo ṣe itọju awọn ọmọ Rẹ̀ ni ilẹ ti ẹnikẹni kò i gbé rí yii. Iṣoro ati aini wọn pọ̀ ni igba otutu akọ́kọ́. Yatọ si pe awọn eniyan wọnyii ti wọn kọkọ bẹrẹ si i tẹdo sibẹ ni iṣoro lati ri ounjẹ ti o to jẹ, wọn tun ri i pe awọn ara India ti o wà nibẹ ti kò si fẹran wọn yoo tun wa dóti wọn, wọn o si jà wọn ni olè, tabi nigba miiran wọn a fi iná sun ile wọn eyi ti o ṣoro pupọ fun wọn lati kọ̀. Ṣugbọn awọn Arinrin-ajo wọnyii, bi o tilẹ jẹ pe wọn rẹwẹsi nigba pupọ, wọn kò sọ igbẹkẹle wọn ninu Ọlọrun nù. Nigba ti igba ooru de, ọ̀gbin oko wọn dagba lọpọlọpọ, wọn si ri ounjẹ ọpọlọpọ ko jọ ni igba ikore ti wọn fi pamọ de igba otutu. Wò o bi ọkàn wọn ti kún fún ọpẹ́ to fun ipese Ọlọrun! Wọn kò gbagbe Ọlọrun nigba ti wọn kọ́ ile wọn ti wọn si ri ounjẹ kó jọ de igbà otutu ti n bọ̀ wá. Wọn kede ọjọ pataki kan ni ọjọ idupẹ fun Olugbala wọn, Ẹni ti o mu wọn la iṣoro nla nla kọja ti O si pese fun aini wọn.

### Ọkàn Ọpẹ

Ni oorọ̀ ọjọ Idupẹ kin-in-ni awọn eniyan naa gbara jọ pọ lati inu gbogbo ibugbe wọn ni ayika sinu ile-isin kekere naa ti a fi igi kọ́. Wọn wá pẹlu ọkàn ti o kún fun ọpẹ si Ọlọrun fun ibukun ti ile kan ninu eyi ti wọn le bu ọlá fun orukọ Rẹ̀, ile ijọsin nibi ti ijọba kò le paṣẹ idiwọ kankan. Wọn mọ̀ pe iṣoro ṣi tun wà sibẹ ni ọjọ iwaju, ṣugbọn Ọlọrun kọ ha ni O ti mu wọn de ihin nipa iṣẹgun, Oun ki yoo ha maa ṣamọna wọn lọ sibẹ pẹlu iṣẹgun? Wo iru ayọ̀ nla ti o kun inu ọkàn wọn ni ọjọ naa, pe wọn jẹ́ ominira ninu àyà ati ninu ẹri-ọkàn wọn! Lori ilẹ naa ti a ro laaarin aginju ni awọn eniyan kan pade, wọn si kọ orin iyin si Oluwa ikore Ẹni ti kò gbagbe awọn ti Rẹ̀.

### Orin Mose

O daju pe wọn ranti awọn Ọmọ Ọlọrun miiran ti wọn jade pẹlu igboya lori ileri Ọlọrun ti a si ti ṣamọna wọn lọ si "ilẹ ileri" kan. Boya wọn kọ orin Mose ti awọn Ọmọ Israẹli kọ nigba ti a mu wọn jade kuro ni oko-ẹrú ni Egipti: "Emi o kọrin si OLUWA, nitoriti o pọ̀ li ogo; ati ẹṣin ati ẹlẹṣin on li o bi ṣubu sinu okun. OLUWA li agbara ati orin mi, on li o si di igbala mi: eyi li Ọlọrun mi, emi o si fi iyin fun u; Ọlọrun baba mi, emi o gbé e leke … Ninu ãnu rẹ ni iwọ fi ṣe amọ̀na awọn enia na ti iwọ ti rapada: iwọ si nfi agbara rẹ tọ́ wọn lọ si ibujoko mimọ́ rẹ" (Ẹksodu 15:1-19). Awọn Arinrin-ajo wọnyii le wi pe Amin si orin naa, nitori dajudaju aanu Oluwa ni o ti ṣamọna wọn jade gẹgẹ bi O ti ṣamọna awọn Ọmọ Israẹli pẹlu.

### A Tun Odi Jerusalẹmu Kọ́

Bakan naa ni Nehemiah ti jẹ aṣaaju awọn ọmọ Ọlọrun kan nigba ti o mu wọn jade lati oko-ẹru Babiloni lati tun Jerusalẹmu kọ́. Ni ọjọ kan bi o ti n ṣe iṣẹ rẹ gẹgẹ bi iranṣẹ ninu agbala ọba keferi kan, o gbọ́ ipe Ọlọrun lati lọ tun Ilu Mimọ́ nì ti o ti wà ni ahoro fun ọpọlọpọ ọdun ṣe. O ko awọn eniyan diẹ lẹyin rẹ, pẹlu aṣẹ ọba, o bẹrẹ si iṣẹ lati tun odi Jerusalẹmu mọ. Lẹyin ọpọlọpọ idojukọ ati laalaa, a pari iṣẹ naa, awọn eniyan naa si pejọ fun iyà si mimọ́, "lati fi ayọ̀ ṣe iyà si mimọ́ na pẹlu idupẹ ati orin, pẹlu simbali, salteri, ati pẹlu dùru." "Li ọjọ na pẹlu nwọn ṣe irubọ nla, nwọn si yọ̀ nitori Ọlọrun ti mu wọn yọ̀ ayọ̀ nla, aya wọn ati awọn ọmọde yọ̀ pẹlu, tobẽ ti a si gbọ́ ayọ̀ Jerusalẹmu li okere réré" (Nehemiah 12:27, 43).

### Imoore Dafidi

Ni akoko Dafidi, nigba ti a mu Apoti-Ẹri wá si Jerusalẹmu lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli ti bori awọn Filistini, awọn eniyan naa yọ ayọ̀ nla. Dafidi ni ẹni ti o kọ ọpọlọpọ Psalmu, o si kọ ọkan ni akoko yii: "Ẹ fi ọpẹ fun OLUWA, ẹ pè orukọ rẹ̀, ẹ fi iṣẹ rẹ̀ hàn ninu awọn enia. Ẹ kọrin si i, ẹ kọ orin mimọ́ si i, ẹ mã sọ̀rọ gbogbo iṣẹ iyanu rẹ̀ … Ẹ kọrin titun si OLUWA gbogbo aiye; ẹ ma fi igbala rẹ̀ hàn lati ọjọ de ọjọ … Nitori titobi li OLUWA, o si ni iyin gidigidi" (1 Kronika 16:8-36). Alabukun-fun ni awọn eniyan naa ti wọn fi ogo fun Ọlọrun fun idasilẹ Rẹ̀, ti o ri ọwọ Ọlọrun ninu iṣẹgun wọn.

**Ẹni Alabukun-fun**

Gbogbo awọn eniyan wọnyi ni o fi agbara wọn ṣiṣẹ, wọn jagun wọn si ṣẹgun, wọn fi igbadun ti ara du ara wọn ki wọn ba le ṣe ifẹ Ọlọrun; wọn si layọ ninu ifi ara rubọ ti wọn ṣe. Ki ni ohun ti o n mu inu awọn eniyan dùn? Ki i ṣe nini gbogbo owo ti wọn n fẹ, tabi awọn ohun ti a n fi owo rà. Ọpọlọpọ awọn alaini ni o n rò pe bi awọn ba ni owo bi ti awọn ọlọrọ awọn yoo layọ, ṣugbọn Bibeli sọ fun wa pe ifẹ owo ni gbòngbò ohun buburu gbogbo. Nibi ti ẹ̀ṣẹ ba wà, ko si inú didun nibẹ. "Ninu ẹrin pẹlu, aiya a ma kãnu; ati li opin ayọ̀, a di ibinujẹ" (Owe 14:13). Sọlomọni ni ọrọ̀ lọpọlọpọ; o sọ nigba kan pe ohunkohun ti oju oun ba fẹ, oun a si ni i. O kọ́ awọn ilé nla nla, o ni awọn ọgba daradara, o ṣe awọn adagun omi fun igbadun ara rẹ, o si ko wura ati fadaka jọ yi ara rẹ̀ ká. O ni ju eyi ti ẹnikẹni ni Jerusalẹmu ti ni ri lọ. Njẹ o ha ni inu didun? Ohun ti o wi ni yii: "Nigba ti mo wò gbogbo iṣẹ ti ọwọ mi ṣe, … si kiyesi i, asan ni gbogbo rẹ̀ ati imulẹmofo, ko si si ère kan labẹ õrun" (Oniwasu 2:11). Gbogbo iṣẹ ọwọ wa, gbogbo nnkan ti a ni, ki yoo mu inu wa dun.

Ta ni ẹni naa ti o jẹ alabukun-fun? "Ibukún ni fun awọn enia na, ti ẹniti Ọlọrun OLUWA iṣe" (Orin Dafidi 144:15). "Ibukún ni fun ọkunrin na ti o wá ọgbọ́n ri" (Owe 3:13). Eyi nì n tọka si ọgbọ́n ti ẹni iwa-bi-Ọlọrun: "Ibẹru OLUWA ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n" (Orin Dafidi 111:10).

Bi inu eniyan ba dùn, oun yoo maa yin Ọlọrun logo lati inu ọkàn rẹ̀ wá; ko ṣe e ṣe pe ki oun má yin Ọlọrun; iyin yoo maa rú soke ninu ọkàn rẹ̀ sibẹ bi o tilẹ jẹ pe o wà ninu ìṣẹ́ tabi ipọnju. Ẹni kan bere lọwọ Haydn, ogbogi ninu orin kikọ silẹ, idi rẹ̀ ti orin rẹ̀ fun ijọsin ni ile-isin fi maa n mu ori eniyan yá nigba gbogbo? O dahun pe "Kò ṣe e ṣe fun mi lati mu ki o yatọ si eyi. Emi n kọ akọsilẹ gẹgẹ bi ero ọkàn mi ti rí: nigba ti mo ba n rò nipa Ọlọrun, ọkàn mi a kún fun ayọ to bẹẹ ti orin naa yoo maa jó ti yoo si maa fò soke, lati ori kalamu mi: niwọn igba ti Ọlọrun si ti fun mi ni ọkàn ti o n yọ̀, ẹ o fi ori ji mi pe mo n sin In pẹlu inudidun."

Ayọ nì ti ifẹ Ọlọrun n fi sinu ọkan wa maa n mu ki iṣẹ wa fuyẹ; ki yoo rẹ eniyan pupọ nidi iṣẹ rẹ bi orin ba wà ninu ọkan rẹ. Nehemiah ni, "Ayọ̀ OLUWA on li agbara nyin" (Nehemiah 8:10). Ayọ ti o wà ninu ọkan yoo fara hàn ni oju; nigba ti awọn ẹlomiran ba si ri ẹrin musẹ naa awọn pẹlu yoo rẹrin. A, ayọ ti o maa n de ba ni ninu fifi gbogbo rẹ silẹ patapata fun Ọlọrun! "Nitori ayọ̀ li ẹ o fi jade, alafia li a o fi tọ́ nyin: awọn oke-nla ati awọn oke kékèké yio bú si orin niwaju nyin, gbogbo igi igbẹ yio si ṣapẹ́" (Isaiah 55:12). (Wo Ẹkọ kọkan-le-lọgbọn ninu Iwe Kẹta).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti awọn Arinrin-ajo wá si Amẹrika?

2 Njẹ awọn nikan ni o jiya fun Ọlọrun?

3 Ki ni awọn Arinrin-ajo ṣe lẹyin ti wọn kore ohun-ọgbin wọn?

4 Ta ni ẹni ti o mu awọn Ọmọ Israẹli jade ni Egipti, yatọ si Mose?

5 Nigba ti Nehemiah pari titún odi Jerusalẹmu kọ́, awọn ta ni ni ipin ninu iyasi-mimọ naa?

6 Ta ni ẹni ti inu rẹ dun?